# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,595 MONDAY DECEMBER 27, 1965 (2D)

## Awon Kan Dana Sun Moto!

SHAGAMU:- Ninu Irohin kan to de ile iṣẹ wa ni owurọ ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kerinlelogun oṣu yi ni a ti gbọ wipe rogbodiyan to nṣẹlẹ ni ilu Shagamu ko ti de opin ati pe ọpọlọpọ ile ni awon enia ti dana sun ti awon enia ti padanu emi wọn ninu ebunti o nṣelẹ ni ilu na lati ọsẹ meji sẹhin irohin ti o tun de ile iṣẹ wa ni a ti a gbọ wipe awọn enia kan dana sun moto ayọkẹlẹ ti Ọgbẹni Adio Moses ti ile iṣẹ Igbimọ eto iṣẹ fun apapọ Ijọba Naijiria

Irohin na fi ye wa pe lojiji ni awon enia na yi Ọgbẹni Adio Moses ka eyiti o jẹ pe Ọgbẹni Moses si sa asala fun ẹmi rẹ to fi jẹ wipe moto ayọkelẹ rẹ ni awọn enia si dana sun ni adugbo Ijoku Shagamu ni ọjọ ojo 'Bo ti iṣe ojo ketalelogun oṣu yi

Irohin fi ye wa pe iṣẹlẹ na ṣelẹ nigbati Ọgbẹni Moses fẹ pada si Ibadan lati Eko, eyiti awon enia na fi kolu ti nwon fi dana sun moto rẹ eyiti nomba rẹ jẹ LK 5963

Ninu irohin lati owo oniwe irohin wa ni ilu Ṣhagamu ni o ti ṣe alaye pe Ọgbẹni Adio Moses duro ni ilu Shagamu lati lọ wo ọrẹ rẹ kan ni adugbo Cinema Road eyiti o jẹ wipe nigbati o npadabọ lati lọ si Ibadan ni awọn enia na da duro ti ọwon si fi epo moto si ara moto rẹ yika ki nwọn to dana sun moto na

Wo Oju Ewe Keta

Iyaafin Oloye Awolowo So Pe:-

# ODODO NI O LE GBE ORILẸ — EDE LE'KE

IBADAN:- Ni opin ọsẹ ti o kọja lọ yi ni Iyaafin Oloye Awolọwọ, ẹniti iṣe aya Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre, ki gbogbo awọn enia Orilẹ ede ilẹ Naijiria ni ile ati ni ẹhin odi ku ewu ọdun ibi Jesu Kristi ti iṣe Keresimesi.

Iyaafin Awọlọwọ tun ki gbogbo awọn enia wipe, ki awọn ku ọdun eyi ti a nṣe lọwọ yi, ki a si ma dupẹ wipe ọdun na ba gbogbo wa laye ati alafia, ninu eyiti Ọlọrun tun ka wa kun, ti o si tun ka wa yẹ wipe, ki ẹmi gbogbo wa le ri ọdun na.

Iyaafin Oloye Awolọwọ ni, "Bi a ba wo gbogbo awọn nkan ti Ọlọrun ti ṣe fun wa ninu ọdun na, ao ri wipe, o lọ, o si tun ye ki a maa fi ọpẹ fun Ọlọrun ninu ohun gbogbo fun Ifẹ Rẹ lori wa lọsan ati ni oru."

"Ṣugbọn o ṣe gbogbo enia ni aanu wipe, ni iru asiko yi, ti gbogbo awọn enia nyọ fun ọdun na, ioanujẹ ati aifaiyabalẹ lo wa fun awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

"Kini o si mu gbogbo awọn nkan wọnyi wa loni, tabi kini sun awọn enia Ipinlẹ na de iru aye ti awọn wa ni oni yi, bi ko ba ṣe ẹmi aisotitọ, ati aiṣododo ati agabagebe, ninu eyiti o ti mu ọpọlọpo enia padanu ohun ini wor., awọn ti nwọn ko mọ ọnọ ti nwọn ko mọ ẹsẹ, gẹgẹbi ọrọ Mimọ Ọlọrun ti sọ pe, Nigbati awọn ọlẹṣẹ ba njẹya olododo a ma pin ninu rẹ.

"Ṣugbọn a dupẹ lọpọlọpọ wipe awọn enia kan ti dide aisinyi wipe, awọn yio pari gbogbo ohunti o nṣẹlẹ yika Ipinlẹ na eyiti ko fi awọn enia lọkanbalẹ ti o si tun mu ki Ipinlẹ na su gbogbo enia lati ma a de paapajulọ awọn Onisowo ti nwọn nfẹ lati da iṣẹ aje silẹ yika Ipinlẹ na loni,

"Nipa sise bayi, gbogbo awọn ọmọ Ile iwe ti nwọn ki ba ti ma ri iṣẹ ṣe tabi ti o yẹ ki gbogbo wọn ti wa ninu ile iṣẹ kan, gbogbo wọn ti di ẹniti ko ni iṣẹ lọwọ, nwọn si di alairi iṣẹ ṣe



## Iyaafin Oloye Awolowo

Iyaafin Awolọwọ wa kesi gbogbo awọn enia ti nwọn sọ wipe awọn yio pari gbogbo rukerudo, edeaiyede ati rudurudu ti o wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun ni asiko yi wipe ki gbogbo wọn gbiyanju la ti rii wipe, nwọn ṣe ohun gbogbo ni ọna ti o to ati ni ọna ti o yẹ.

Ju gbogbo rẹ lọ, ki awọn "onilaja" na rii daju wipe, awọn fi idi iwadi ti nwọn fẹ ṣe lelẹ lori otitọ ati ododo, ki nwọn maṣe pe ohunti o ba dudu ni ohunti o funfun ki nwọn maṣe pe ohunti ko dara ni ohun dadara, bi o ba jẹ wipe nitootọ ni nwọn ni ifẹ awọn enia Ipinlẹ yi lọkan ti nwọn si fẹ pari ija ati edeaiyede na ni tootọ.

Iyaafin Awolọwọ tun ṣe afikun ninu eyiti o fi ki awọn enia ku ewu ọdun wipe, nigbayowu ti awọn enia na yio ba maa sọrọ ki nwọn maṣe maa sa fun ọrọ otitọ ati ododo.

Nigbati awọn enia na ba fẹ sọrọ ti nwọn sọ wipe awọn yio sọ, ki nwọn maṣe sa fun otitọ ọrọ, ṣugbọn nigbati nwọn ba mọ ododo ti nwọn si fi aye silẹ lati sa fun ododo, bi o tilẹ jẹ wipe ẹri ọkan wọn yio maa da wọn lẹjọ, sibẹ na, nwọn ko ni le sọ ọrọ na ni ọna si o tọ ti o si tun yẹ, nitoripe nwọn nbẹru lati sọ otitọ, eyi si mu wọn sa kuro lọdọ ododo.

Bi awọn enia na ba se bayi ninu ohunti nwọn fẹ ṣe, ki nwọn mọ dajudaju wipe nwọn ko wa alafia awọn enia, nwọn ko si tun fẹ pari ọrọ ti o wa nile yi, bikose wipe, nwọn tun fẹ dakun ọrọ na ni

Iyaafin Oloye Awolọwọ na wa sọ wipe, Orisa, bi o ba le gba mi, jọ mi gẹgẹbi o ba ti da mi, ati ọrọ Ọlọrun ti o tun sọ wipe, ẹniti o ba mọ rere iṣe ṣugbọn ti ko ba ṣee, ẹṣẹ ni fun un."

O tun sọ fun gbogbo awọn enia na wipe, "Okun kun ati Imole ki iṣe ọrẹ ara won. Bẹẹni awọn mejeji ko si jẹ pade pẹlu ki ba ṣe ni ọsan tabi ni oru

Iyaafin Awolọwọ sọ wipe, bi enia ba ... wọ ẹhin ... yio ri wipe, ọdun ti o kọja lọ yi ko mu alafia wa, ki iṣe ni Naijiria nikan sa gbọn yika gbogbo aiye ni, ṣugbọn ti Ipinlẹ Iwọ Irun loo wa pelo ke, ti o si tun ju gbogbo won lọ.

Bi enia ba s... se ki yesi awọn ohun ti o ... da gbogbo nkan wọnyi silẹ, oluwarẹ yio ri wipe, awọn enia ko le lati maa se ododo ati otitọ mọ ninu idawole, wọn nwọn si fẹ maa fi ohun ti igba kan bo ọkan ni..., eyi ti ko le mu alafia ati ifẹ wa larin awọn enia

Iyaafin Awolowo sọ wipe ohunti o nfa gbogbo awọn nkan ti o nṣẹlẹ na wọnyi ni wipe awọn enia korira ọrọ otitọ — nwọn si fẹran iro gẹgẹbi ọrọ Mimọ, Ọlọrun ti sọ wipe, ọmọ araiye fẹran okunkun ju imole lọ, nitoripe, iṣẹ owo wọn buru.

Wo Oju Ewe Kẹfa

# SHOYINKA ẸHIN RE KOMI BURU

Ni ọjọ Kerin osu kejila odun 1964
Ariwo gba'le Okiki gbo'de
Ẹlẹkun osun
Alariwo npa pe.
Ilẹ mọ lẹhin Ọkunrin
Akukọ tun wa kọ
Lẹhin Ọgọtọ Ọmọ enia
Shoyinka Iyẹru Ọkin
Omo Abasu Joruko
Ọmọ Olọfa mọjọ
Ija ija kan ti
Nwọn ja L'efa
Ile Ololomi oju ta l'ose ?
O s'oju isu ninu ebe
Otun soju poro oko loko
Ki ba soju Oloko
Iba la won
X X X X
Kaasa Ig
Ibẹn lọ nipọri
Fọlọnsọ fi wa' lẹ
O lọ si ọrun
Are maa bọ
Fọlorunsọ lọ
Ko mu iaa lọ

## Lati Ọwọ
## Joseph Ọla Okunlọla

Baba oninu rere
Ka biñu ẹru ri
Yio ma la wọn lọ ni
Bẹni ko wipe
Ki a wọn iwọfa
Kekeke ki o ma sa iwo rẹ
Akikanju ninu ọkunrin lọ

X X X X X X X

Bi o ba lalya ki o seke
B, o ba ranti iku Shoyinka
Ki o sọ otitọ
Foloruosọ ti wi bẹ ẹ
Ti ṣe bẹ
Ko pe kolowo
Ko mọ lowo
Bẹni ko je ki'wọfa
Ki o ma a sanwo rẹ
Yio ma la wọn lọ ni
Kini Shoyinka ṣe
Ti o jẹbi
Fọlọrunsọ ṣe bẹ
O lọ ninu ọmọ Shoyinka
Igi ti o ba tọ
Ki ipe ninu igbo
Omi ti o toro
Ọgan nigbẹ
Añaju ọmọ niwọn
Ki pẹ lawujọ
Ma a sun gbagbe
Awọn abure rẹ
Pẹlu awọn ọmọ rẹ
O di ọdun meji gbako
Ti o ti fi wa silẹ
Ti a ndaro rẹ
Pa oninu rere
Wa nilẹ bẹun
A fọgbo fogbo
A poyi ọdan
Poyi ọdan
A ko ri ẹni wa
Ẹni wa, wa wa o
A sun ko lala
Ri Folorunsọ
Ti o fi wa silẹ lọ

X X X X X X

Ẹ ba dakun jare
Ẹ je ki a ma ṣe rere
Nitori a ko mọ asiko
Ti ọlojo yio de
Edumare dakun
Jare an wa lhw
Ki iku ka Ire rere
Mo gbogbo wa lowo
Hal bayi ni asiko
Ọmọ enia
Shoyinka ṣe isẹ rere
Ki o to filẹ bora
Bi aso
Kini ki a wi ?
Kini k a so
Ti Isẹ rere ni
Tabi Sure
Shoyinka orun rere
X X X X X
Jọwọ maa jẹ Ookun
Dakun maa jẹ ekolo
Gbogbo obun ti nwọn
Ba njẹ Lalade ọrnn
Ni ki o ma bawon jẹ
Bi o ba rilẹ Onimọ
Jowo maa ya bẹ
X X X X
Aiye toto to funun
Ile aiye ile asan
Aiye Wahala
Aiye Idamu
Edumare maa se ni
Tẹletẹle amin.
X X X
Jọwọ ba wa ki
Baba wa Owon
Iyẹru Okin
Omọ Olofa mejọ
Shoyinka ku
Shoyinka si tun ku
Folorun gbere o
O di Arinnako
O di oju ala
Ki a to tun rira
N tototo awa ko
Lo laiye
Igba ni tiwa
Bi aiye ti yẹ
Folorunsho Shoyinka
Edumare dakun
Jowo jẹki orun
Ko ro lorun
Edumare ye
Dari awon ẹṣẹ rẹ ji
A tuba, tọ si afẹfẹ rere

Y X X X Y X X X X

Oluwa ba ni so
Awon ti o ku
Jowo Oluwa ba ni
Mu ile to file lowo
Ma dẹru ba
Awon omo rẹ
Oluwa Olugbala wa
Edumare wa pẹlu
Awon ẹbi to fi le lo
Di awon na mu
Jeki nwon to
Baba fun Omo
Folorunso
Folorunso Shoyinka
O di gba o se o

# Eniti O Ji Simenti Gbe W'ewon Osu Mesan

YABA:- Ni ojo ojo'Ru ti ise ojo kejilelogun osu yi ni Adajo ile ejo kekere ti Yaba ti pase pe ki Okunrin kunlekunle kan Oyebanji Oseni eni Ogbon odun yara lo fi ewon osu mesan jura lori esun pe odaran na ji Simenti ninu ile itaja kan ti ise ti Ogbeni Adebanyo Ogunsanya ni Suru-Lere Adajo na tun pase pe ki nwon na Okunrin Odaran na ni bilala mefa ni idi.

Ninu oro Olopa to ba Odaran na se ejo ni o ti se alaye fun Adajo ile ejo na pe Oyebanji Oseni lo fo Sobu Ogbeni Adebanjo Ogunsanya ni nomba 5, Okigbo Street Suru-Lere ni ogbonjo osu karun odun yi.

Ninu oro Okunrin Odaran na lati fi gba ara re sile ni o ti se alaye fun ile ejo pe on ko lo jale tabi fo Sobu gegebi esun ti olopa na ka si on lese.

ugbon Ogbeni Busari Oriola ti ise Eleri Ijoba ti o si tun je Direba ti Odaran na gba lati fi ko Siment na se alaye fun ile ejo pe Oyebanji si gba on lati lo ba on fi moto ko Siment na ni adugbo Okigbo Street Suru-Lere.

Ogbeni Oriola tun se alaye pe oju on ni Oyebanji se lo fo Sobu na ti o nko awon Simenti na jade eyiti awon enia kan fi kegbo.

Ogbeni Busari tun se alaye fun ile ejo pe on mo apo simenti ti odaran na fe gbe nigbati awon enia na fi pa ariwo titi o fi salo Sugbon ninu oro ti odaran na ro fun Adajo ile ejo na lati fi gba ara re sile ni e ti se alaye pe on nlo si Alaka Street lati lo ba nwon kun ile kan eyiti awon enia na fi beresi kegbe pe on ole titi nwon fi mu on.

Ninu oro Adajo ile ejo na ni Ogbeni Adelayo Awolesi ti se alaye pe on ko gba gbogbo oro ti odaran na so lati fi gba ara re sile ati pe Adajo na tun bere pe o di igba melo ti odaran na ti lo si ewon ri?

Olopa to ba odaran na se ejo lo wo inu iwe won o si da Adajo na lohun pe o di emeje ti odaran na ti lo si ewon eyiti ise ni Apapa Yaba, Ikeja ati awon ibi miran ti nwon ti se Idajo ewon fun un.

Odaran olosa na si tun ro Adajo ile ejo na lati ni oju anu re si on ati pe on ki yio se be mo odaran olosa na tun so otito ni ikehin pe on paro ni akoko ati pe aiya on lo ja nigbati on fi so be tele sugbon Adajo ile ejo na se alaye pe on se ni oju anu si iru olosa bayi ninu kotu on.

---


GBOGBO ARA ILU NKO ORIN IYIN ATI OGO

NIPA **DYAMRIN** TONIK

ALE-BI-ALE Egbogi Tonik iyanu, tilun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mo daju fun Agbara ati Ajebidan ise l ra aebalagba Okunrin ati Obinrin gbogbo

Bi are ara ba nmu o, ni gbakugba fun wahala tabi ise sise ti o ko le jeun dara dara, tabi ki o maie sun dada de okan losan tabi awon saa ara re gbogbo ki sefun daradara ti Emi Breath inu ko ba kule daradara won ise tabi wahala sise tabi inu awon ailera gbogbo nyin ti ojo ori (age) ba ti koja ogbon odun si adori tabi ube lo mo daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfe lari so ara di tu pafapata inu re a jalo eran ara re ti o g hunjo yio bi yabo dada tiAra re yio gbe kankan ni ugba yio sao pelu ioq m adeu brode o iyen di bos



Waterloo Medecine Stores
8 Palm Church Streer Lagos P. O Box 333

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos
ATI NI SOBU
ISE OLODUMARE DISPENSARY OKE BOLA IBADAN


---

**E ma a ka Iwe Irohin Imole Ki e si maa Polowo Oja Nyin sinu re Lojojumo**

---


# GBANJO!

NOVEMBER 15th — DECEMBER 30th 1965



Iwe itumo Ala.
[illegible]
j[illegible]bi O[illegible]o, [illegible]i
[illegible]gun Aj[illegible]bid[illegible]n
3s6d di 1s6d

Iwe Afose Isedale Yoruba ati Psalmu Ajebidan.
3s 6d di 2s

Turari 2s 6d Paketi di 1/-

o le ri iwe wonyi ra lodo :-

J. O. SHOYINKA P. O. Box 159, Mushin.
SHOYINKA ni 9, Iyalla Street, Mushin.

# OBA TI AAFIN RẸ JONA PA ARA RE

IJẸBU - IGBO:- A gbọ sọ igba nu ni irohin ri o kan awọn en a ni opin ọsẹ to kọja nigbati Oba Joel Ogu lana ti ilu Ododeyo ni ẹba Ilugun Alaro ni agbegbe Ijẹbu-Igbo lọ pa okun so nigbati o ri iafin rẹ pe gbogbo rẹ ni o fi jọna di e ru pẹlu awọn dukia ti owo rẹ pọ ti o jona sinu aafin rẹ.

Gẹgẹbi irohin ti Onirohin wa fi ranṣẹ lati Ijẹbu-Igbo ni o ti sọ pe, awọn channa kan lọ ka Oba na mọ inu ile rẹ ti nwọn fẹ ṣe leṣe, ko duro mu ẹwu, pata niken ni o wa nidi rẹ ni o ba oju ferese jade to sálọ sinu igbo kan

Bi o ti lọ tan ni awon channa yi ba da epo petirolu si gbogbo ara inu ile ati ode aafin Ọba Ogunlana ni nwọn ba dana sun gbogbo rẹ ti o di eeru.

Lẹhin wakati die ni ọba na ba pada wa wo ohunti o ṣẹlẹ si aafin rẹ, bi o ti ri ri gbogbo rẹ to di eeru ni o ba ka owo le ori ti o bẹrẹ si sọkun kikoro

Irohin fi ye wa pe ọba Ogunlana ba lọ si odo awọn eni rẹ kan bi o ti sun ni iyara ni o ba tilẹkun mọri ninu irohin na tun so pe nigbati ilẹ mọ ti o yẹ ki oba na jade ti ko jade ni nwon ba bẹrẹsi kan ilẹkun ṣugbọn nwọn ko gbo ki o soro ni nwọn ba si ilẹkun na ni ipa

Nwon ni bi nwon ti ṣi ilẹkun ti nwo nwa oba na kakiri ni nwon ba ri nibi ti o ti pa arare natipata.

Orisirisi irohin ni a tun ri gbọ lori awọn enia ti o nfi ifẹ inu awọn han lodi si Ibo ti awọn di ni Ipinlẹ Iwọ Orun ni ojọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi.

A gbọ lati ilu Odogbolu pe awọn kan ti tun lọ jo ile ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ Ol ye Olu Fayẹmi ti o tun je oludari ibiṣe Ijoba Iwọ Oron ti o mojuto erọ asọ—rọmagbesi pẹlu eyiti o fi ẹniti nsọrọ kan, awọn k ti mọ eniti o dana sun ile na di bi a ti nkọwe irohin yi lọwo.

Ati ile pẹlu awọn ohun ini ti o ṣẹlẹ ni ọjọ na le ni eebẹrun ponun,

Bakanna ni nilu Shagamu ni awọn kan tun lọ jo ile ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ kan ti o wa ni adugbo kan ti o njẹ Lant wa i hin fi ye wa pe Ọgeni Lawal ti si kuro nile ti pẹ ti awọn enia rẹ ko le sọ nat ibiti Ọkunrin na wa

A tun gbọ pe ọkan ninu ọlọpa ti ofi ara gba ibọn ni ilu Ajebandele ti ku si ile iwosan bayi.

Ni Owode ni agbegbe Egba ile ti nwon sun kolo nka ninu ile ti nwon jo okan je ti ogbe i Raufu Fatoki

## YE IRAWO RE WO

AQURIUS (Jan 22 Feb 20) Igbadun yio de ara rẹ yio si le loni, fuu irohin adadun kan ti o gbọ loni alafia yio de si gbogbo ara rẹ.

PISCES (Feb 21 Mar 20) Ara rẹ yio le tobẹ ti o jẹ wipe gbogbo awọn iṣẹ ti iwọ ko ti le ṣe ri bi iwọ yio ma ṣe igbẹhin rẹ yio dun ede koyede to ṣẹlẹ laipẹ yi o kuro

ARIES (Mar 21 April 20) Ṣọra nitoripe ijọgbọn kan yio sẹlẹ loni, Nṣe ni ki o ku ara rẹ nijanu bi o ba le ṣe pẹlẹpẹlẹ ọwọ rẹ yio tẹ ohun ti o nfẹ pẹlu irohin.

TAURUS (April 21 May 20) Iwọ yio ma tẹsiwaju dara dara ki o si uupẹ wipe ori rẹ ti pe iwọ o si gọọ irohin alayọ kan ki o si nifẹ ajum se, jẹki ori rẹ pe nigbati o ba nba ọga re sọrọ.

GEMINI (May 21-June 21) Ire ni ọjọ oni, nitori iwọ yio ma tẹsiwaju ti nkan ko ni ṣoro fun ọ, iwọ yio gburo ire kan lati ona okere, ayọ ati idunnu yio wa larin iwọ ati iyawọ rẹ

CANCER (June 22-July 23) Ọjọ wahala ni oni yio jẹ fun ọ, ohun ti o dara ni pe ki o ṣagbara rẹ ki gbogbo okan le ma dara, jẹki ohun kan ti o nfẹ ṣe di chin ọdun Keresi-mesi

LEO (July 23-Aug 22) Ire yio ma dagba soke fun ọ, iwọ yio si ni ọpọlọpọ ilọsiwaju bi o ba ri ere diẹdiẹ je, ki o si bẹrẹ si kọwe si awọn ọrẹ rẹ

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Alafia ara yio to ọ, iwọ yio si ma fi igbadun ṣe ayọ, şa ma dupẹ l iwọ enikan ti o lọ ba sọrọ ohun kan ti o ti nda ọ lamu ni iwọ yio yanju kedere

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Lagbara Ọlọrun ati lagba ra egbogi iwọ yio ni agbara lati yanju gbogbo isoro to mbẹ fun ọ ati arẹ ti o nṣọ ọ lẹnu

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Iwọ yio ri aye lati ṣe gbogbo ohunti o nfẹ lau se bi o ti wu ki idiwọ na pọ to sa se suru

SAGITTARIUS (Nov 23—Deb 21) Ire rẹ yio ma tẹsiwaju tobẹ ti o jẹ wipe kiakia ni iṣẹ rẹ yio ma anju ni pawowo ile ae yio si roju

CAPRICORN (Dc 22 Jan 21) Iṣẹ yio pọ fun ọ loni ṣugbọn iwo yio ni tẹlọrun pẹlu rẹ iwọ yio gbọ irohin ayọ nipa awon bi iṣẹ owo ṣiṣe yio si joko si ọ lọwọ


# Kereo Kere o!
# AkiyesiPataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanunhanuu Egbogi na LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ilẹ Naijiria

A wa na njẹwọ ni Igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jama ti olowoki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imoran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan ọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamotase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ soya tabi pe ileri fun gbogbo awọn ti ami di tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbonsẹ deede, inurirun ngbakugba ara wiwo, Esaari chin didun sisan ati aiko riran kedere ko doro buruku ara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni ki ṣjak ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ ṣe enia nipa sis di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ORỌ IJAPARA SI LEWU PẸLU

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla si'e mejo ato (7/-6 pere Igo kekere șiio mẹrin abo (4/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

# Egbẹ UPGA Ni Ọrọ Akerele Ati Kotoyẹ Ko si Ogbọn nibẹ

IBADAN:-Awọn ẹgbẹ UPGA ti fesi ọrọ kan ti meji ninu ẹgbẹ Dẹmọ sọ sinu iwe Iroyin ibẹrẹ ọsẹ yi lori Ibo magomago ti nwọn di laipẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun, ẹgbẹ UPGA sọ pe awọn ẹgbẹ Dẹmọ ni o da wahala yi silẹ ti nwọn npe arawọn ni Olugbala ọmọ Yoruba.

Ninu esi ọrọ ti nwọn fun Ọgbẹni N. A. B Kotoyẹ ati Ọgbẹni Akerele ni ẹgbẹ UPGA to wa ni Ibadan ti so pe gbogbo okan ati ifọro ati wahala to de Ipinlẹ Iwọ Orun losi yi awọn omo ẹgbẹ Dẹmo lo fa gbogbo rẹ

Ninu oro nwon ni nwon ti so pe, awon tio npe arawon Olugbalani awon Yoruba ni o nda nkan silẹ nwon koto gba arawon la dipo pe nwon yio wa gba ẹlomiran la won ko pa ẹtu won ko jẹki ẹtu lo bena ni nwon ko jẹki ẹniti yio ẹtu pa ẹtu, ẹ ko le gba omo Yoruba la ẹniti yio gba omo Yoruba la nwon ko jẹki nwon gba nwon la

Irohin na tun ,de sọ awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmo ko fun awọn enia lati sin Ọlọrun nwọn gẹgẹbi Ofin ati pe, nwọn ko tun fun ọmọ Yoruba laaye lati yan awọn Olugbala nwọn.

Irohin na tun sọ pe, awon ẹgbẹ Dẹmọ ti sọ ara wọn di Olugbala, ṣugbọn awọn Dẹmọ ti gbagbe pe gẹgẹbi ọmọ ilẹ Naijiria ni Ipinlẹ Ila Orun ati Agbedemeji Ipinlẹ Iwọ Orun nfẹ alafia fun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, nwọn tun sọ siwaju sii pe, laisi alafia, irẹpọ ko le si ilọsiwaju wo ati pe ko si le si aṣe yọri.

Nwọn wa so pe, bi Ọlọla Ọdẹlẹyẹ, Fani Kayọde ati Kotoyẹ jẹ ọkan ni u Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun nwon ni kọkan ilọsiwaju ọmọ Yoruba bayi, ṣugbọn laipẹ ọjọ ikuku ti ẹgbẹ Dẹmọ fi bo owo Aje Ipinlẹ yi yio kasẹ nilẹ.

Ẹgbẹ itẹsiwaju wa sọ pe, yio jẹ ibakuna bi awọn ọmọ Ipinlẹ Iwọ Orun ti o nsan owo ori ba nsan owo ori ti awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ wa ni ọwọ na bi omi ojo, bẹni ọna ẹburu ni nwọn gba gori Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Laipẹ yi jọjọ ao da bere ina alafia ati ifọkanbalẹ ni Iwọ Orun Naijiria bi ẹgbẹ Dẹmọ ba si tun nba Ijọba Alapapadodo lọ ni Ipinlẹ na, o to asiko ti awọn enia fi opin si iwa familete ntu tọ ti ẹgbẹ nhu ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Ẹgbẹ UPGA ni loruko Ọlọrun ati ti ilẹ Naijiria ki ẹgbẹ Dẹmọ tete lọ ronupiwada ki nwọn si faramọ ero awọn enia ibo ti nwọn di ni ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi, ki nwọn ye ṣe ilẹkuṣe ti Ọgbẹni Ọjẹrin ọa ṣe ti si apakan. Awọn ọmọ Yoruba ti ri iyọnu to lori ile, moto, dukia ti enia jijo nitori ifẹ owo ni awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ṣe jẹki awọn okan Wọnyi ṣ,lẹ.

"Ijọba ti awọn enia ko yan sori aga ni ẹgbẹ Dẹmọ jẹ, ko si ẹniti ko mọ pe ẹgbẹ Dẹmọ ko le gba ara wọn la, ki enia fi ọgbọn ori gbe o h u n gbangba pe nwọn kole mu ina d'oko. Atipe yio jẹ itanjẹ bi a ba lọkan si pe, alafia yio pada si ilẹ Yoruba bi Ijọba ẹgbẹ Dẹmọ ba si tun wa lori aga.

Fun enia Ipinlẹ Iwọ Orun ni Ijọba ti nfẹ loni, ẹo ri pe, ẹ tun fun ni alafia.


## Ila Kini Eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
LORI ERIN META NI

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ An O dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idun

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu o ni ri erin meta ni nwọn mu un ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu elitaja kakiri orile ede yi

DISTRIBUTORS

AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Decemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS



BERE FUN OJULOWO ADI_ELEGBO

## "Congreve's odo Form--Ointment'



Atamatase ni egbogi " ADI-ELEGBO" yi i fun itọju gbogbo orisirisi "EGBO—ẸSẸ" ni kiakia bi o ti wun ki jọ rẹ ti le pẹ to, Adielegbo yi ko ni ẹgbẹ nipa wipe awa ko idọti ni bi ẹrẹ gbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara .Lẹhinna oju egbo ti o ba jin sinu yio jeki oju re ru wa soke, yio si pọn daradara run bakaru ko si mọ werewere ni yio si san patapata Alafia de si ọ niyẹn :

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won si sale iwe yi ni ogbe ranṣe lọ ra. Bibeko awon Eleru abi onijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba ẹ ra o.

Bere egbogi yi ni ṣobu awon :—ọ

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos

UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

NO 1,595 MONDAY DECEMBER 27, 1965 (2D)


## Nwon Jẹ Ọba Hausa Ni Oshogbo

OSHOGBO:— Gbogbo ilu Oshogbo lo kun fun ayọ nigbati Oba Ataoja ti ilu Oshogbo fi Mallam Garuba Tshofo, jẹ Ọba Saabo ni ilu Oshogbo ki ayẹyẹ ifi Joye na to bẹrẹ ni awọn Hausa to wa ni ilu Oshogbo ati agbegbe rẹ ti bẹrẹsi maa jo kakiri arin ilu ti nwọn nkorin ilu wọn, ti nwọn tun nkorin yin alaiyeluwa Ọba Samuel Adenle Ataoja ilu Oshogbo.

Mallam Garuba Tshofo ni o gba ipo Mallam Umoru ti o lo ogun ọdun lori aye Ọba Saabo, ti o ku ninu ọdun yi.

Bi ayẹyẹ ifini joye na ti bẹrẹ ni afin Oba Adenle ti ku fun ogunlọgọ ati Ọkẹaimọye enia ti nwọn wo bi nkan ti nlọ si, awọn Hausa to wa ni Ekun Ọshun ni nwọn ran aṣoju wa.

Gbara ti nwọn fi Mallam Tshofo joye tan ni akọwe awọn Hausa to wa ni Oshogbo Mallam Usuman Sansau, dupe pupọ lọwọ Ọba Adenle fun ifẹ rẹ ti o ni si awọn Hausa ti o wa ninu ilu rẹ, o tun dupe lọwọ awọn enia Oshogbo fun ife ti nwọn ni si awọn, o wa tun fi ọpẹ fun Igbimọ ti o nfi enia joye ti Ijọba Ibilẹ Oshogbo fun o ṣa ti wọn ṣe ti gbogbo re fi yọri si rere.

O pari ọrọ rẹ nipa ọe, awọn yio maa wa alafia awọn Yoruba paapa ọmọ Oshogbo ti iṣe Aje yio fi maa gbilẹ sii, ti owo obi pelu ẹran malu ati awọn ohun ọgbin ko fi bọwọ sori ninu ilu na.

Awọn enia patakipataki ni o wa sibi ayẹyẹ na, ninu wọn ni Ọga Ọlọpa bi Ọgbẹni J. L. Alao adajọ Ijọba ti o ngbe Oshogbo Ọgbẹni Ọla'ere Ayinbo, Alaga Ijọba Ibilẹ Oshogbo Ọgbẹni Bello Adeyẹmọ.

# ROGBODIYAN NLA TUN BẸSILẸ NI ẸGBADO

ABẸOKUTA:- Ninu irohin ti o tun nde si ile iṣẹ wa lati kutukutu owurọ ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹrin'elọgun osu yi ni a tun gbọ pe rogbodiyan miran ti tun bẹrẹsi ṣẹlẹ ni jakejado Ipinlẹ Iwọ Orun Nijiria lori eto abayọri idibo si Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun eyiti awọn enia Ipinlẹ na di ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi.

Ninu irohin ti o de ile iṣẹ wa ni a ti gbọ wipe awọn enia kan ti dana sun ile iṣẹ ti Ijọba Ibilẹ ti Adogbẹssa eyiti o ti jẹ wipe gbogbo ile iṣẹ ti Ijọba Ibilẹ na lo jona di eeru patapata.

Bakanna ni irohin tun fi ye wa pe awọn enia kan tun dana sun ile iṣẹ ti Ijọba Ibilẹ ti ilu Oke Odun ni ẹkun Ẹgba to fi jẹ wipe gbogbo awọn ẹru ti Ijọba Ibilẹ na lo jona patapata.

Ninu irohin to tun de ọwọ wa lati ilu Abẹokuta ni a ti gbọ wipe ọkẹaimọ ye awọn Olori ẹgbẹ Dẹmọ ati Amugbalẹgbẹ ọmọ Dẹmọ (NNDP) ni nwọn ti binu fi ẹgbẹ Dẹmọ silẹ ti nwọn si ti pada sinu ẹgbẹ itẹsiwaju (UPGA)

Ninu awọn olori ẹgbẹ Dẹmọ to binu kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) ti nwọn si pada sinu ẹgbẹ UPGA ni Ọgbẹni Grimo Ayegoro ti iṣe Alaga ẹgbẹ Dẹmọ ni Agọka Abẹokuta.

Ninu iwe ti Ọgbẹni Ayegoro fi binu kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ ni o ti ṣe alaye pe on kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ ni o ti ṣe alaye pe on kuro ninu ẹgbẹ na lori ero ọkan on ati lori ero ọkan ti awọn ẹbi on. Ọgbẹni Ayegoro tun ṣe alaye pe o ti jẹ ohunti o han gbangba si on loju pe ẹgbẹ Dẹmọ ki iṣe ẹgbẹ Oṣeju kan ti awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun fẹ ati pe ẹgbẹ Dẹmọ si jẹ ẹgbẹ ọdalẹ patapọ.

Ọgbẹni Ayegoro tun ṣe alaye pe awọn enia kan lo si ṣi on lọna lati ma ṣe ẹgbẹ Dẹmọ ni adugbo oe. O ni on ti mọ daju pe ẹgbẹ Dẹmọ ko fẹ ire mọ enikankan bikoṣe pe ti ara wọn ni nwọn njadu.

Ninu ọrọ olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ni adugbo Agọka Ọgbẹni A. N. Adenekan ni o ti ṣe alaye pe iwe ti Ọgbẹni Aiyegoro fi kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) ni o ṣe alaye pe nwọn ti fi ranṣẹ si awọn enia to wa ni Agọka, Abẹokuta.


## Asalam Alaikum Jammah !

### Nafila Oru Oṣu Ramadan.

Lati Ọwọ ALUFA AKEWULA

ORU ỌJỌ KARUN 27/12/65 :— Irun mẹjọ, Salamọ mẹrin lori iduro Irun kọọkan, ṣo ke:-Fatiha kan; Alamunasiraha kan ati Kul-hua-Allahu mẹta

KA IROHIN—IMỌLẸ FUN NAFILA TI ỌLA


Lati Oju Ewe Kini

Ṣugbọn ki awọn ọlọpa ti wa ilu Shagamu to de ibiti awọn enia na ti da na sun mọto Ọgbẹni Moses ni irohin fi ye wa pe gbogbo mọto na lo ti jona patapata ti o si ti di eeru.

Irohin fi ye wa pe gẹgẹbi awọn enia na ti bẹrẹsi fi epo mọto kun mọto rẹ ni Ọgbẹni Adio ti salọ sinu ile kan to wa tosi lati da abo bo ẹmi rẹ Ṣugbọn Ọgbẹni Adio Moses ti lọ fi oran na sun ni Tesan awọn ọlọpa ti ilu Shagamu

Irohin tun fi ye wa pe awọn enia kan da a sun ile Ọgbẹni A. Tejmọla ni adugbo kan ti awọn npe ni Latawa Shagamu ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹrinlelogun oṣu yi.

Irohin fi ye wa pe awọn enia na lọ si ile Ọgbẹni A. Tejumọla pẹlu epo mọto lọwọ ti awọn si fi epo mọto ku ile ni yika ki nwọn to dana sun ile na.

Ṣugbọn gbogbo wahala ti awọn ọlọpa ti nwọn wa ni ilu Shagamu ṣe lati le pa ina na lo ja si asan eyiti o fi jẹ wipe gbogbo ile na lo si jona patapata.

Irohin fi ye wa pe awọn ọlọpa ti mu enia mẹtala ni ilu na lori ohun ti o ṣẹlẹ na Bakanna ni awọn ọlọpa ati Ṣọja tun lọ si ilu Shagamu bayi lati lọ ṣe eto gẹgẹbi eto ofin alafia yio fi wa ni ilu na.

LATI OJU EWE KẸFA

Ko si inu ẹati odun rara si gbogbo awọn ohunti o nṣẹlẹ bisisiyi nipa dida, na sun ile, ati ipania bi a ti ngburo rẹ ni ojojumọ yi.

Ṣugbọn awọn enia kan ntan arawọn jẹ nipa wipe ki nwọn maa sọ wipe awọn enia kan ni awọn nda nkan na siẹ ti nwọn ki iṣe ara Ipinlẹ Iwo Orun.

Ni ipari ọrọ rẹ, Iyaafin Awolọwọ sọ wipe, bi enia kan ba fẹ ki gbogbo nkan wọnyi ki o pari, ki awọn maṣe maa ka awọn enia kan si ẹniti o wa ni ipo ẹhin, nitoripe, Ọ ọran kanna ni o da gbogbo wa.

O wa gbadura wipe, ki Ọlọrun jọwọ ninu Anu Rẹ ki o mu ẹmi aiṣodo kuro ninu enia, ki nwọn si le maa sọ otitọ ni aye yowu ti nwọn ba wa, ki nwọn si mọ wipe, ohunti awọn nṣe ni oni, itan ni ni ọla, atipe ohun ti awọn ba ṣe, ọmọ wọn yio jẹ nibẹ lẹhin ọla.

O wa sọ bayi wipe, 'Ki Jesu Kristi ọmọ Ọlọrun ti iṣe Ọba alafia jẹki gbogbo enia le maa gbe papọ ni alafia ati pẹlu ifẹ.

Printed & Published By Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos 27/12/65